
**Lati ọwọ Ààrẹ**
**Thomas S. Monson**



# Mímú Iṣẹ nã Yá

Njẹ́ o mọ̀ pé Ijọ ímúpadàbọ̀sípò ti dàgbà tó ọdún méjìdínlọ́gọ́rũn kí ó tó ní awọn ẽkàn ọgọ́rũn? Ṣùgbọ́n kò tó ọgbọ̀n ọdún lẹhin nã, Ti Ijọ ti ṣe ètò awọn ẽkàn ọgọ́rũn rẹ̀ kejì. Àti pe lẹ́hìn ọdún mẹjọ péré lẹ́hìn rẹ̀ Ijọ ti ní awọn ẽkan tí ó lé ní ọgọ́rũn mẹta. Loni a ti rinlẹ̀ pẹ̀lú awọn ẽkàn tí ó lé ní ẹgbẹ̀rún méta.

Kínni ìdí ti dídàgbà yĩ fi ń wáyé ní ìwọ̀n eré sísá bẹ̃? Njẹ́ ó jẹ́ nítorípé wọn ti mọ̀ wá dáradára sĩ? Njẹ́ ó jẹ́ nítorípé a ní awọn ilé ìjọsìn tí ó wuni?

Awọn nkan wọ̀nyí ṣe pàtàkì, ṣùgbọ́n ìdí tí Ijọ ṣe ń dàgbà lonĩ ni pé Oluwa ti sọ pé yío rí bẹ̃. Nínú Ẹ̀kọ ati Awọn Májẹ̀mú, O sọ pé, "Kiyesĩ, Emi o mú iṣẹ mi yá ní àkókò rẹ̀."[1]

Àwa, gẹ́gẹ́bí ọmọ ẹ̀mí ti Baba wa Ọ̀run, di rírán wá sí orí ilẹ̀ ayé ní àkókò yĩ kí a lè kópa nínú mímú iṣẹ́ ńlá yĩ yá.

Oluwa kò tĩ fi ìgbà kan sọ rí, sí òye mi, pé isẹ́ Òun jẹ́ ti ara ikú nìkan. Dípò bẹ̃, iṣẹ́ Rẹ̀ gba ayéraye mọ́ra. Mo gbàgbọ́ pé Òun ń mú iṣẹ Rẹ̀ yá ninu ayé ti ẹ̀mí. Mo gbàgbọ́ báknanã pé Oluwa, nípasẹ̀ awọn ìránṣẹ́ Rẹ̀ lọ́hũn, ń pèsè ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn ẹ̀mí lati gba ìhìnrere nã. Iṣẹ́ wa ni lati wá awọn òkú wa jáde ati lẹ́hìnnã kí a lọ sí tẹ́mpìlì kí á sì ṣe awọn ìlànà mímọ́ èyítí yío mú awọn ànfãní tí àwa ní lọ bá awọn tí wọn wà ní ẹ̀hìn ìbòjú.

Olukúlùkù Ẹ̀nìyàn Mímọ́ ti ọjọ́ Ìkẹhìn tí ó dára nínú ayé ti ẹ̀mí ni ó ń ṣiṣẹ́, ni Ààrẹ Brigham Young wí (1801–77). "Kínni wọn ń ṣe níbẹ̀? Wọn ń wãsù, wãsù ní gbogbo ìgbà, ati pe wọn ń pèsè ọ̀nà fún wa lati mú kí iṣẹ́ wa yá ní kíkọ́ awọn tẹ́mpìlì ní ìhín yĩ ati ní ibòmíràn."[2]

Nísinsìnyí, iṣẹ́ ìtàn ìdílé kò rọrùn. Fún ẹ̀yin wọ̃nnì tí ẹ wá lati Scandinavia, mo pín nínú sísúni yin. Fún àpẹrẹ, ní ìlà Swedish mi, orúkọ baba mi àgbà ni Nels Monson; orúkọ baba tirẹ̀ kĩ ṣe Monson rárá ṣùgbọ́n Mons Okeson. Orúkọ baba Mon jẹ́ Oke Paderson, ati orúkọ baba rẹ̀ ni Peter Monson—tún padà sí Monson lẽkansĩ.

Oluwa ń retí ìwọ ati èmi lati ṣe iṣẹ́ ìtàn ìdílé wa dáradára. Mo lérò pé ohun àkọ́kọ́ tí a gbọ́dọ̀ ṣe bí a bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ wa dáradára ni lati ni Ẹ̀mí Baba wa Ọ̀run pẹ̀lú wa. Nígbàtí a bá gbé ní òdodo bí a ti ṣe mọ̀ lati gbé, Òun yío ṣí ọ̀nà fún ìmúṣẹ ti awọn ìbùkún tí a ń wá pẹ̀lú ìtara ati ãpọn.

A ó ṣe awọn àṣìṣe, ṣùgbọ́n ìkọ̀ọ̀kan nínú wa kò lẽ já fáfá nínú iṣẹ́ ìtàn ìdílé láì jẹ́ pé a kọ́kọ́ jẹ́ òpè. Nítorínã, a gbọ́dọ̀ ju ara wa sínú iṣẹ́ yĩ, a sì gbọ́dọ̀ gbaradì fun awọn òkè gígun díẹ̀. Èyí kĩ ṣe iṣẹ́ tí ó rọrùn, ṣùgbọ́n Oluwa ti gbẽ lé orí rẹ, O sì ti gbẽ lé ori mi.

Bí o ti ń lépa iṣẹ́ ìtàn ìdílé, iwọ yío rí ara rẹ bí o ti ń sáré sínú awọn ìdènà, iwọ yío sì sọ fún ara rẹ pé, "Kò sí ohun míràn ti mo le ṣe." Nígbàtí o bá de irú ìkórita nã, wólẹ̀ ní orí ẽkún rẹ kí o si bẽrè lọ́wọ́ Oluwa lati ṣí ọ̀nà, Òun yío sì ṣí ọ̀nà fún ọ. Mo jẹ́rĩ pé èyí jẹ́ òtítọ́.

Baba Ọ̀run ní ìfẹ́ awọn ọmọ Rẹ̀ ninu ayé ẹ̀mí gẹ́gẹ́ ní ìwọ̀n bí Òun ti ní ìfẹ́ ìwọ ati èmi. Nipa iṣẹ́ ti gbígba awọn òkú wa là, Wòlĩ Joseph Smith sọ pé, "Ati pe nísinsìnyí bí awọn èrò nlá ti Ọlọ́run ti ń yára wá sí àṣeyọrí wọn, ati awọn ohun ti a ti sọ nínu awọn Wòlĩ toń di mímúṣẹ, bí

ìjọba Ọlọ́run ti di gbígbé kalẹ̀ lórí ayé, ati awọn ètò àtijọ́ ti awọn ohun nkan di mímú padà sí ipò, Oluwa ti fi ojúṣe ati ànfãní yi hàn wá."[3]

Nipa awọn ẹni àtijọ́ wa ti wọn ti kọja lọ lâì ní ìmọ̀ ìhìnrere, Àarẹ Joseph F. Smith (1838–1918) kéde, "Nípasẹ̀ awọn akitiyan wa ní síṣojú fún wọn, awọn ẹ̀wọ̀n ìgbèkùn wọn yío jábọ́ lára wọn, ati pe òkùnkùn tí ó yí wọn ká yio ká kúrò, kí ìmọ́lẹ̀ kí ó le tàn sí orí wọn ati pe wọn yío sì gbọ́ ninu ayé ẹ̀mí nipa iṣẹ́ tí a ti ṣe fún wọn lati ọwọ́ awọn ọmọ wọn, wọn yío sì yọ̀ pẹ̀lú yin ní ṣíṣe awọn ojúṣe wọ̀nyí."[4]

Ẹgbẽgbẹ̀rún lórí ẹgbẽgbẹ̀rún awọn ọmọ ẹ̀mí ti Baba wa Ọ̀run ni wọ́n wà tí wọn kò gbọ́ orúkọ Krístì rárá kí wọn ó tó kú tí wọn sì lọ sínú ayé ẹ̀mí. Ṣùgbọ́n nísĩnyí a ti kọ́ wọn ní ìhìnrere wọ́n sì ń dúró de ọjọ́ nã nigbatí ìwọ ati èmi yio ṣe ìwádĩ tí ó yẹ lati pa ọ̀nà mọ́ kí a le lọ sí inú ile Oluwa kí a sì ṣe é fún wọn iṣẹ́ tí wọn kò le ṣe fún ara wọn.

Ẹ̀yin arákùnrin ati Arábìnrin mi, mo jẹ́rĩ pé Oluwa yío bùkún wa bí a ti gbà tí a sì jígìrì sí ìpèníjà yĩ.

---

### ÌDÁNILẸ́KỌ̀ LÁTI IṢẸ́ YÌÍ

Ronú nipa ìtàn àsọtúnsọ kan lati inú ìwé ìtàn ìdíle rẹ kí o sì ṣe àbápín ìtàn yĩ pẹ̀lú awọn ti o ń bẹ̀wò. O lè fẹ́ lati lo awọn ìbẽrè inú abala ti awọn ọmọdé ti ọ̀rọ̀ Àjọ Alákóso Gbogbogbò (ojú ewé kẹfà) lati gba awọn tí o ń bẹ̀wò níyànjú lati ṣe àbápín awọn ìtàn tiwọn. Ṣe àgbéyẹ̀wò kíka Doctrine and Covenants 128:15 ati sísọ ọ̀rọ̀ lori pàtàkì ṣíṣe awọn ìlànà tẹ́mpìlì ní ìgbẹnusọ fun awọn ẹni àtijọ́ wa.

#### ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́

1. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 88:63.
2. *Ìdánilẹ́kọ́ ti Àwọn Alákóso Àgbà ti Ìjọ: Brigham Young* (1997), 67.
3. *Àwọn Ìkọ́ni ti Àwọn Àare ti Ìjọ: Joseph Smith* (Ọdún 2007), 475.
4. *Ìdánilẹ́kọ́ ti Àwọn Alákóso Àgbà ti Ìjọ: Joseph F. Smith*.

## ỌDỌ́

## Njẹ́ Mo Le Gbádùn Títolẹ́sẹ̀sẹ?

**Lati ọwọ́ Emma Abril Toledo Cisneros**

Mo kópa nínú ìlépa ti ẽkàn wa lati to awọn orúkọ ẹgbẹ̀rún lọ́na ãdọ́ta lẹ́sẹ̃sẹ. Ní àkọ́kọ́ díẹ̀ síi. Ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà kíkọ awọn ìdì ti mo ń ṣiṣẹ́ lé lórí mã ń ṣòro, ati pe nígbàmíràn mo mã nfẹ́ lati dá wọn padà kí n sì ṣiṣẹ́ lórí òmíràn. Ṣùgbọ́n mo rĩ pé bi olukúlùkù bá ronú bẽ, awọn ìdì wõnnì yío di fífi sílẹ̀ di ìgbẹ̀hìn. Mo le fi ojú inú wo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlà awọn ènìyàn tí wọn ń dúró nínú ayé ti ẹ̀mí, mo sì pinnu lati tẹ̀síwájú ní títiraka lati ka awọn orúkọ wõnnì kí n sì ṣe àtúnkọ wọn láì ṣe àṣìṣe.

Mo kọ́ \ẹ̀kọ́/lati ní ìfẹ́ fún awọn ènìyàn wõnnì. Mo ní òye pé wọ́n nílò ìrànlọ́wọ́ nitõtọ́, ati pe awa bákannã nílò ìrànlọ́wọ́ lati ọ̀dọ̀ wọn. Mo wá ní òye dáradára sĩ pé ètò pípé Baba Ọrun fi gbogbo eniyan sínú àgbéyẹ̀wò. Nigbati a bá tẹ̀lé ìmísí ati awọn ẹ̀kọ́ awọn olùdarí yíyàn Rẹ̀, a ó rí ãnú ati ìfẹ́ àìlópin Rẹ̀.

Títòlẹ́sẹ̀sẹ ti jẹ́ ìrírí kan tí ó kúnfún ìfẹ́ fún mi. Mo kọ́ ẹ̀kọ́ lati mọ ríri ati lati ní ìfẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn nkan nipa ìwé ìtàn ìdílé. Bákannã mo gba awọn ẹ̀bùn tí ó ní iye ńlà lati ọ̀dọ̀ Oluwa wa nipa gbígbọ́ràn sí ohun tí ó rọrùn bĩ kíkópa nínú títo lẹ́sẹ̀sẹ.

*Olùkọ̀wé ngbé ni Veracruz, Mexico.*

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

## Mọ Awọn Ìtàn Rẹ

Awọn òbí ati awọn òbí òbí rẹ ti ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn ìrìn àjò tí o kò tilẹ̀ mọ̀ nípa awọn kan! Awọn ìtàn wọn kan yío mú ọ rẹ́rĩn, wọn sì le ràn ọ lọ́wọ́ lati ní ìgbàgbọ́ ninu Baba Ọrun Ṣùgbọ́n awọn àgbàlagbà náa mã ń ní ìmọ̀lára ojútì nígbàmíràn. Lo àwọn ìbẽrè wọ̀nyí lati ràn wọ́n lọ̀wọ̀ ṣe ìrántí díẹ̀ lára awọn ìtàn tí wọn fẹ́ràn jù kí o sì ṣe àkọsílẹ̀ tàbí kí o ya àwòrán awọn ìdáhùn wọn.

1. Sọ fún mi nípa awọn ohun mẹ́ta tí ó mú inú rẹ dùn jù tí o lè rántí.
2. Kíni àsìkò tí ó jẹ́ ìgbà tí ara tì ọ jù?
3. Sọ fún mi nipa ọjọ́ tí a bí mi.
4. Kínni ohun tí o fẹ́ràn lati ṣe nígbàtí o wà ní kékeré?
5. Báwo ni o ṣe ni ẹ̀rí ti ìhìnrere tìrẹ?

© 2014 lati ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/14. Àyípadà èdè ti *First Presidency Message, June 2014*. Yoruba.10866 779

# Iṣẹ Ìránṣẹ Àtọ̀runwá ti Jésù Krístì: Àlapẹrẹ

*Ẹ fi tàdúrà tàdúrà ṣe àṣàrò ọ̀rọ̀ yìí kí ẹ sì wá lati mọ̀ ohun tí ẹ ó ṣe àbápín. Báwo ni níní òye ìgbé ayé ati iṣẹ́ ìránṣẹ́ ti Olùgbàlà ti ṣe àlékún ìgbàgbọ́ yin nínú Rẹ̀ ati bùkún awọn tí ẹyin ń bójútó nípasẹ̀ ìbẹniwò kíkọni? **Fún ìmọ̀ síi**, lọ sí reliefsociety.lds.org*

**Ìgbàgbọ́, Ìdílé, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí ni apákan nínú oníruurú àwọn Iṣẹ́ Abẹniwò Kíkọni tí ó ńfi awọn abala ti iṣẹ́ ìrànṣẹ Jésù Olùgbàlà hàn.*

Bí a ti ń gba awọn ẹlòmíràn níyànjú, a ń di atẹ̀lé Jésù Krístì nitõtọ́, ẹnití o fi àpẹrẹ lélẹ̀ fún wa. Àarẹ Thomas S. Monson sọ pé: "Awọn tí wọn wà nínú àìní yí wa káàkin. . . . Àwa ni ọwọ́ Olúwa níhĩnyi lórí ilẹ̀ ayé, pẹ̀lú ìyọ̀nda lati sìn ati lati gbé awọn ọmọ Rẹ̀ sókè."[1]

Linda K. Burton, àarẹ gbogbogbò Ẹgbẹ́ Arannilọ́wọ́, kọni: "pẹlu ìgbìdánwò, ọ̀kọ̃kan wa le fẹ́rẹ̀ dàbí Olùgbàlà tán bí a ṣe ń sìn awọn ọmọ Ọlọrun. Lati ran wa lọ́wọ́ [sọ̀rọ̀ ìyánjú sí] awọn ẹlòmíràn, yío wù mí lati dábã awọn ọ̀rọ̀ mérin lati rántí: 'Àkọ́kọ́ wòye, lẹ́hìnnã sìnrú.' . . . Bí a ti ń ṣe bẽ̀, a ń pa awọn májẹ̀mú mọ́, ati iṣẹ́ ìsìn wa, bí ti Àarẹ Monson, yío jẹ́ àrídájú ti jíjẹ́ ọmọlẹ́hìn wa."[2]

A lè gbàdúrà ní àrãrọ̀ lati le rí awọn ànfãní lati sìn awọn ẹlòmíràn. "Baba Ọ̀run yío tọ́ ọ sọ́nà, ati pe awọn angẹ̀lì yío ràn ọ́ lọ́wọ́," ni David L. Beck sọ, Alákóso gbogbogbò ti awọn Ọ̀dọ́mọkùnrin. "A o fi agbára fún ọ lati bùkún awọn ìgbé ayé ati lati kó awọn ọkàn yọ."[3]

## Láti Àwọn ìwé Mímọ́

Matteu 20:25–28; 1 Nífáì 11:27–28; 3 Nífáì 28:18

## Láti inu Ìtàn Wa

Ni ibi ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbò ti Oṣù Kẹwã 1856, Àarẹ Brigham Young (1801–77) kéde pé awọn ẹni ìṣãjú oni kẹ̀kẹ́ ẹṣin ṣì ń la awọn ìlẹ̀ kọjá ati pé olukúlùkù nilati ṣe ìrànlọ́wọ́ Láti ṣa awọn nkan èlò jọ fún wọn ní kíákíá. Lucy Meserve Smith ṣe àkọsílẹ̀ pé awọn obìnrin "bọ́ awọn aṣọ àwọ̀lékè wọn [awọn yẹ̀rì títóbi], awọn ìbọ̀sẹ̀, ati gbogbo ohun ti wọn ba le fi sílẹ̀, ní ibẹ̀ gangan ní Tabernacle, kí wọn sì kó wọn sínú awọn wágọ́nù."

Bí awọn ẹni ìṣãjú kíkóyọ nã ṣe dé sí Salt Lake City, Lucy kọ̀wé, "Emi kò tĩ gba . . . ìtura púpọ̀ ninu iṣẹ́ kankan tí mo ti ṣe ní ìgbé ayé mi, irú ìṣọ̀kan ti ìmọ̀lára borí. Mo kàn nilati lọ sí ibi ìkẹ́rùsí kan kí n sì sọ ohun ti mo fẹ́ di mímọ̀; bi ó bá jẹ́ aṣọ, a ó wõn wò lâì bẽ̀rè iyekíye."[4]

Àarẹ George Albert Smith (1870–1951) sọ nípa gbígba awọn ẹlòmíràn níyànjú: "Ìdùnnú wa ní ayérayé yío jẹ́ ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì sí ọ̀nà tí a fi jọ̀wọ́ ara wa lati ran awọn ẹlòmíràn lọ́wọ́."[5]

### Gba Èyí Yẹ̀wò

**1.** Bawo ni àdúrà ṣe le tọ́ wa lati jẹ́ ohun èlò ni ọwọ́ Oluwa?

**2.** Bawo ni gbígba awọn ẹlòmíràn níyànjú ṣe le ràn wá lọ́wọ́ lati pa awọn májẹ̀mú wa mọ́?


**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Thomas S. Monson, "Kínni Mo Ti Ṣe fun Ẹnìkan Lónì?" *Liahona,* Nov. 2009, 86.
2. Linda K. Burton, "Lákọ̀kọ́ Wòye, Lẹ́hìnnã kío Sìn," *Liahona,* Nov. 2012, 78, 80.
3. David L. Beck, "Your Sacred Duty to Minister," *Liahona,* May 2013, 56.
4. Lucy Meserve Smith, nínú *Daughters in My Kingdom: The History and Work of Relief Society* (Ọdún 2011), 36–37.
5. George Albert Smith, in *Daughters in My Kingdom,* 77.


© 2014 lati ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/14. Àyípadà èdè ti *Visiting Teaching Message, June 2014.* Yoruba. 10866 779